Kíkọ̀wé bèrè fún Ilé Àìwọ́n:

# Ìtọ́ni Owó Àpawọlé Olùbèrè

Ìtọ́ni Owó Àpawọlé



## NÍPA ÌTỌ́NI YÌÍ

Owó àpawọlé ***rẹ*** ṣe pàtàkì púpọ̀ fún ìbéèrè ilé àìwọ́n rẹ.

Ìtọ́ni yìí ń fi hàn ọ́ bí a ti ń ṣírò owó àpawọlé rẹ fún ilé àìwọ́n.

Èyí kìíṣe ìbéèrè ilé. Kò ní sọ fún ọ bí ó bá máa gba ìbùgbé kan. Ṣùgbọ́n ó le ràn ọ́ lọ́wọ́ láti fún ọ ní ìdáhùn tó ṣe déédé nípa owó àpawọlé rẹ.

Tí a bá fìwé pè ọ́ sí ***ìpàdé láti ṣàrídájú àmúyẹ rẹ***, wàá ní láti mú àwọn ìwé àkọsílẹ̀ wá láti ṣàrídájú gbogbo àlàyé tó wà lórí ìbéèrè rẹ.

Àwọn ọ̀rọ̀ ní ***wíwọ̀ tó sì dúdú*** ni a ṣàlàyé ní ojú ìwé 10, “Àwọn Gbólóhùn Ìrànwọ́.”

## INÚ:


KÍNNI OWÓ ÀPAWỌLÉ? 2

IRÚ OWÓ ÀPAWỌLÉ WO NI Ó KÀN? 3

OWÓ ÀPAWỌLÉ LÁTI IBI-IṢẸ́ 4

OWÓ ÀPAWỌLÉ LÁTI IṢẸ́ ÀDÁNI 5

OWÓ ÀPAWỌLÉ LÁTI ÀWỌN ORÍSUN MÍRÀN 7

OWÓ ÀPAWỌLÉ TÍ A KÒ ṢÀFIKÚN 8

ÀWỌN ÌBÉÈRÈ TÍ A Ń BÈRÈ NÍGBÀ GBOGBO 9

ÀWỌN GBÓLÓHÙN ÌRÀNWỌ́ 10


*Ìkọ́sílẹ̀: Ìwé yìí ni a ṣe láti pèsè àlàyé gbogbogbò nìkan. Àkóónú dá lórí Ìwé-ìléwọ́ Ìbùgbé HUD 4350.3 àti HPD àti Ìtọ́ni Ìtajà HDC. Àwọn àpẹrẹ owó àpawọlé kò ṣàlàyé gbogbo àwọn ipò ètò ìṣúná tó ṣeéṣe.*

# Kínni owó àpawọlé?

**Ǹjẹ́ ìwọ gba owó láti…**

- Iṣẹ́ kan tàbí ju iṣẹ́ kan lọ?
- Ìṣiṣẹ́ fún ara rẹ?

  *Àwọ́n àpẹrẹ: Awakọ̀ èrò, olùṣerun, ayàwòrán aládàáṣe*
- Àwọn orísun míràn, ní **ìgbàdégbà**?

  *Àwọ́n àpẹrẹ: Àtìlẹ́yin ọmọdé, àwọn ànfàní àìníṣẹ́ lọ́wọ́, owó àpawọlé ààbò aláfikún (SSI), ìfẹ̀yìntì*

Owó yìí jẹ́ ***owó àpawọlé***. O ní láti mọ iye owó tí o ń gbà láti le bèrè fún ***ilé àìwọ́n***.

## ÀWỌN ÌGBÉSẸ̀ LÁTI ṢÍRÒ OWÓ ÀPAWỌLÉ:

**1** **Tọ́kasí gbogbo orísun owó rẹ.**



Owó àpawọlé láti **iṣẹ́ òjọ́** (p. 4)



Owó àpawọlé **iṣẹ́ àdáni** (p. 5)



Owó àpawọlé **àwọn orísun míràn** (p. 7)

**2** **Ṣe ìṣírò àwọn owó iṣẹ́ rẹ ojoojúmọ́ tàbí ti óṣooṣù láti mọ àpapọ̀ iye tí wọ́n jẹ́ lọ́dún***



Owó wákàtí kọ̀ọ̀kan láti ọ̀dọ̀ agbanisiṣẹ́ <u>sáájú</u> kí a tó yọ owó-orí àti àwọn àyọkúrò míràn



***Owó àpapọ̀*** lórí ìpamọ́ ìsanwó (tí a san lọ́sọ̀sẹ̀, gbogbo ọ̀sẹ̀ méjì, abbl.)

**Owó tí o pa láti iṣẹ́-àdáni ni o gbọ́dọ̀ ṣírò bíi **owó ÀMÚRELÉ**, èyí tíí ṣe owó <u>léyìn</u> tí a ti yọ ìnáwó ìṣòwò àti ohun míràn kúrò.*

**Oríṣìí ọ̀nà ni o fi le gba owó àpawọlé**

Àwọn àpẹrẹ díẹ̀:

- Ìwé sọ̀wédowó ní ọ̀sẹ̀ 2
- Àwọn owó àjẹmọ́nú owó ní ìsún kọ̀ọ̀kan
- Èyíkéyìí irú ìsanwó ọ̀sọ̀sẹ̀ tàbí oṣooṣù, bíi àtìlẹ́yìn ọmọdé, àfẹ̀yìntì, tàbí àwọn ànfàní àìníṣẹ́ lọ́wọ́
- Ẹ̀bùn àkókò ìsinmi ní ọdọdún

**Owó àpawọlé ni a le pè ní oríṣìí orúkọ**

Àwọn àpẹrẹ díẹ̀:

- Owó oṣù
- Owó ọ̀sẹ̀
- Àpamọ́wọ́
- Ìsanwó

Gbogbo owó yìí ni ***owó àpawọlé***. Wàá ní láti ṣàfikún rẹ̀ lórí ìbéèrè ilé àìwọ́n rẹ Tí o bá lọ sí ***ìpàdé láti ṣàrídájú àmúyẹ rẹ*** fún ilé àìwọ́n, wàá ní láti mú àwọn ìwé àkọsílẹ̀ wá láti jẹ̀rìísí owó àpawọlé rẹ.

**3** **Ro owó àpawọlé láti gbogbo orísun míràn papọ̀ láti mọ àpapọ̀ *iye owó apawọlé láàrín ọdún.***

**RÁNTÍ**

Láàrín gbogbo ìtọ́ni yìí, o le rí ọ̀pọ̀ àlàyé nípa àwọn ọ̀rọ̀ tó hàn ní ***wíwọ́ dúdú*** lórí p.10, "Àwọn Ọ̀rọ̀ Ìrànwọ́."

**IRÚ OWÓ ÀPAWỌLÉ WO NI Ó KÀN?**

# Irú Owó Wo ni Ó Wà Níbẹ̀?

**Oríṣìí ìsọ̀rí owó àpawọlé 3 ló wà lórí ìbéèrè ilé àìwọn náà.**

## 1 OWÓ ÀPAWỌLÉ LÁTI IṢẸ́-ÒÒJỌ́



Owó tí agbnisiṣẹ́ san fún ọ. Èyí pẹ̀lú owó àjẹmọ́nú, ẹ̀bùn, àfikún àkókò, àti irú ìsanwó míràn. Tí o bá gba fọ́ọ̀mù owó-orí W-2 kan, owó náà jẹ́ ***owó àpawọlé láti iṣẹ́-òjọ́.***

Lórí ìbéèrè náà, ṣàfikún owó náà <u>sáájú</u> àwọn owó-orí tàbí owó míràn ni a ń yọkúrò **(*owó àpawọlé àpapọ̀*).**

**Fún àpẹrẹ:**

- Owó oṣù láàrín ọdún
- Àpapọ iye owó iṣẹ ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ tàbí ti ooṣoṣù ní ọdún kan owó iṣẹ ojoojúmọ tàbí ti ọ̀sọ̀ọ̀s, pẹ̀lú owó lọ́wọ́, tí a san ní ***ìgbà gbogbo***
  - *Àpẹrẹ: Ọ̀sọ̀sẹ̀ • Ọ̀sẹ̀ 2 • Ẹ̀meji láàrín oṣù kan • Oṣoṣù*
- ***Ìgbà Kọ̀ọ̀kan*** ṣiṣẹ́ fún agbanisiṣẹ́ kan
  - *Àwọn àpẹrẹ: Àwọn iṣẹ́ òpin ọ̀sẹ̀ fún ilé-iṣẹ́ ìdáná • Owó ojojúmọ́ (ojúmọ́) àwọn iṣẹ́ ìlera fún ilé-ìwòsàn kan tàbí aṣọjú*
- Iṣẹ́ ìgbà
  - *Àwọn àpẹrẹ: Ìtajà ìgbà ìsinmi • Iṣẹ́ ìgbà oru fún ilé-iṣẹ́ tí ń ṣe òrùlé*
- Owó àjẹmọ́nú
- Ìsanwó ìgbà ìsinmi
- Àfikún àkókò
- Àwọn ẹ̀bùn àti àjẹmọ́nú tí o gbà nígbàdégbà

---

## 2 OWÓ ÀPAWỌLÉ LÁTI IṢẸ́-ÀDÁNI



Gbogbo owó náà tí o gbà láàrín ọdún láti ìṣiṣẹ́ fún ara rẹ, iṣẹ́ tí o ṣe fún oríṣiríṣi agbanisíṣẹ́ láti ìgbà-dé-ìgbà, tàbí jíjẹ́ agbaṣẹ́ṣe aládàáni.

Lórí ìbéèrè náà, pẹ̀lú iye owó <u>lẹ́yìn</u> tí o ti yọ ìnáwó ìṣòwò kúrò àti àwọn àyọkúrò míran **(*owó àmúrelé*).**

**Fún àpẹrẹ:**

- "Owó ìṣòwò (tàbí àdánù)" lórí ìdápadà owó-orí rẹ
- Owó tí o pa lórí ìṣòwò àdáni rẹ
- Ìṣẹ́ tí o ṣe fún oríṣiríṣi agbanisíṣẹ́ láti ìgbà-dé-ìgbà
  - *Àwọn àpẹrẹ: Olùkọ̀wé tàbí òṣèré tí oníbàárà ń sanwó fún tààrà*
- Jíjẹ́ agbaṣẹ́ṣe tàbí alábòójútó àdáni
- Jíjẹ́ olùpèsè iṣẹ́ àdáni
  - *Àwọn àpẹrẹ: Awakọ̀ èrò tó ní/yá ọ̀kọ̀ • olùṣerun tó yá àaye nínú ìsọ̀*
- Iṣẹ́ ìgbà tàbí ẹ̀kọ̀ọ̀kan fún ara rẹ
  - *Àwọn àpẹrẹ: Olùtọ́jú ilé tí onílé ń sanwó fún tààrà • Ṣíṣe ìṣòwò ìdáná tìrẹ ní àkókò oru*

---

## 3 OWÓ ÀPAWỌLÉ LÁTI ÀWỌN ORÍSUN MÍRÀN



Gbogbo owó tí o gbà láàrín ọdún tí a san láti ìgbà-dé-ìgbà, ṣùgbọ́n tí kìíṣe láti ẹnu iṣẹ́. Fún àpẹrẹ: àtìlẹ́yìn ọmọdé, ààbò ìgbàlódé, ìdójútòfò àìníṣẹ́, tàbí ìsanwó èrè.

Lórí ìwé ìbéèrè náà, ṣàfikún owó láti àwọn orísun míràn tí o bá gbàá láti ***ìgbà-dé-ìgbà nìkan*** (ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀, oṣooṣù, ọdọọdún, abbl.).

**Fún àpẹrẹ:**

- Owó ìkọ̀sílẹ̀
- Ìsanwó Òpin Ọdún
- Àwọn Ìpamọ́ Iṣẹ́ Ológun
- Àtìlẹ́yìn Ọmọdé
- Àwọn Àjẹmọ́nú
- Ìdójútòfò Abarapá
- ***Owó Ẹ̀bùn***
- ***Èrè lórí Ìṣòwò***
- Ìfẹ̀yìntì
- Ìrànlọ́wọ́ Ìjọba (Public Assistance, PA)
- Owó Yíyá Ohun Ìní
- Ààbò Ìgbàlódé tàbí SSI
- Àwọn Ànfàní Àìníṣẹ́
- Ìrànlọ́wọ́ Ìtọ́jú
- Ìsanwó Òṣìṣẹ́

IRÚ OWÓ ÀPAWỌLÉ WO NI Ó KÀN?

# 1 Owó àpawọlé láti Iṣẹ́-òòjọ́



***Owó àpawọ́lé láti iṣẹ́-òòjọ́*** jẹ́ owó tí o pa láti ibi iṣẹ́ kan. ó jẹ́ ohun tí agbanisíṣẹ́ ń sanwó fún, ṣáájú owó orí tàbí àwọn àyọkúrò míràn (***owó àpapọ̀***). Lórí ìbéèrè rẹ, ṣàfikún iye owó fún odidi ọdún kan (***owó ọdún kan***). Láti kọ nípa ìsàfikún owó láti ìṣòwo tìrẹ, lọ sí ojú ìwé 5, “Owó àpawọlé láti Iṣẹ́-Àdáni.”

**Ṣí ìwọ, tàbí èyíkéyìí ẹni tí o fẹ́ bá gbé, ní owó àpawọlé láti...?**

- ☐ Owó ọdún kan
- ☐ Owó wákàtí, ojúmọ́, tàbí ọ̀sọ̀sẹ̀
- ☐ Fífi ọwọ́ gba owó
- ☐ Àwọn Àjẹmọ́nú
- ☐ ***Iṣẹ́*** ìgbà kọ̀ọ̀kan fún agbanisíṣẹ́ kan
  *Àwọn àpẹrẹ: Ṣiṣẹ́ fún ilé-iṣẹ́ ìdáná • Ojojúmọ́ (ojúmọ́) àwọn iṣẹ́ ìlera fún ilé ìwòsàn tàbí aṣojú kan*
- ☐ Iṣẹ́ ìgbà
  *Àwọn àpẹrẹ: Ìtajà ìgbà ìsinmi • Iṣẹ́ ìgbà oru fún ilé-iṣẹ́ tí ń ṣe òrùlé*
- ☐ Isanwó ìgbà ìsinmi, àfikún àkókò, ẹ̀bùn, tàbí àjẹmọ́nú

Ìwọ̀nyí ni àwọn orísun ***owó àpawọlé láti iṣẹ́-òòjọ́.*** Tí o bá dáhùn bẹ́ẹ̀ni sí èyíkéyìí nínú ìwọ̀nyí, ṣàfikún iye owó náà sínú abala “Owó àpawọlé láti iṣẹ́-òòjọ́” ti ìbéèrè rẹ.

**BÍ O TI LE ṢÍRÒ OWÓ ÀPAWỌLÉ ỌDÚN KAN**

Ó ṣe pàtàkì láti ṣàfikún gbogbo owó àpawọlé rẹ sínú irinṣẹ́ ọdọdún, tàbí ọlọ́dún kan. Tí a bá ń sanwó fún ọ láti ìgbà-dé-ìgbà (bíi ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀, ọ̀sẹ̀ méjì méjì, ẹ̀ẹ̀meji lóṣù, abbl.), o gbọ́dọ̀ gbé àwọn ìgbésẹ̀ pàtàkì wọ̀nyí láti mọ iye owó rẹ láàrín ọdún.

*Àkíyèsí: Tí o bá ń bèrè lórí ayélujára nínú Ìsopọ̀ Ilé NYC, o kò ní láti ṣe ìṣirò yìí. Ó ń ṣẹlẹ̀ ní aládàáṣe bí o ti ń kún àlàyé owó àpawọlé sínú ìrísí olùlò rẹ.*



**Ẹ̀yàn 1: Ṣàyípadà owó wákàtí sí owó àpawọlé ọdún kan:**

**$** o ń gba owó fún wákàtí 1

**# Wákàtí** o máa ń ṣiṣẹ́ ní ọ̀sẹ̀ 1

**X # ọ̀sẹ̀** o máa ń ṣiṣẹ́ ní ọdún 1

---

**#NAME?**



**Ẹ̀yàn 2: Ṣàyípadà owó ọ̀sẹ̀ tí a ń san nígbàdégbà sí owó àpawọlé ọdún kan:**

Irú ìgbà wo ni a ń sanwó fún ọ́?

- **Ọ̀sẹ̀ kọ̀ọ̀kan:**
  $ sanwó ni ọ̀sẹ̀ kọ̀ọ̀kan x 52 = owó àpawọlé ọdún kan
- **Ọ̀sẹ̀ 2:**
  $ sanwó ní ọ̀sẹ̀ 2 x 26 = owó àpawọlé ọdún kan
- **Ẹ̀meji lóṣù:**
  $ sanwó lẹ́ẹ̀mejì lóṣù x 24 = owó àpawọlé ọdún kan
- **Ẹ̀kan lóṣù:**
  $ sanwó ní oṣoṣù x 12 = owó àpawọlé ọdún kan

**RÁNTÍ**

Owó àpawọlé láti iṣẹ́ gbọ́dọ̀ jẹ́ ṣáájú owó orí àti owó míràn tàbí àyọkúrò tí a ti yọ. (Ẹ̀yí ni a ń pè ní ***owo àpapọ̀***). O gbọ́dọ̀ ṣàfikún owó àpapọ̀ fún òṣìṣẹ́ kọ̀ọ̀kan fún ọdún kan.

OWÓ ÀPAWỌLÉ LÁTI IṢẸ́-ÀDÁNI

# 2 Owó àpawọlé láti Iṣẹ́ Àdáni



***Ówó àpawọlé láti iṣẹ́-àdáni*** jẹ́ gbogbo owó tí o pa láàrín ọdún kan ní ṣíṣe iṣẹ́ fún ara rẹ, ṣíṣe iṣẹ́ fún oríṣiríṣi agbanisíṣẹ́ láti ìgbà-dé-ìgbà, tàbí jíjẹ́ agbaṣẹ́ṣe aládàáni. Lórí ìwé ìbéèrè rẹ, ṣàfikún iye owó fún àpapọ̀ ọdún náà, yàtọ̀ sí àwọn ìnáwó ìṣòwò (***owó àmúrelé***). Tí o kò bá gba iye owó kannáà ní ọdọdún, tún lọ sí ojú ìwé tókàn, "Ṣíṣírò Owó Àpawọlé Ọdún Kan láti Iṣẹ́-Àdáni."

**Ǹjẹ́ Ìwọ, tàbí èyíkéyìí àwọn ènìyàn tí yóo gbé pẹ̀lú rẹ...?**

- ☐ Gba àwọn fọ́ọ̀mù owó-orí 1099
- ☐ Ní ìṣòwò tìrẹ bí
- ☐ Ṣiṣẹ́ bíi olùpèsè iṣẹ́ aládàáni kan bí
  *Àwọn àpẹrẹ: Awakọ̀ èrò tó ní/yá ọ̀kọ̀*
  *• Olùṣerun tó yá ààye nínú ìsọ̀*
- ☐ Ṣiṣẹ́ ìlọkiri
  *Àwọn àpẹrẹ: Òṣèré, olùkọ̀wé, tàbí ayàwòrán tí àwọn oníbàárà ń sanwó fún tààrà*
- ☐ Ṣiṣẹ́ bíi alábòójútó tàbí aládàáni agbaṣẹ́ṣe
  *Àpẹrẹ nísàlẹ̀*
- ☐ <u>Ṣiṣẹ́ fún ara rẹ</u> nígbà kọ̀ọ̀kan tàbí ní ẹ̀kọ̀ọ̀kan?
  *Àwọn àpẹrẹ: Olùtọ́jú ilé tí onílé ń sanwó fún tààrà • Olùtọ́jú ọmọ tí ẹbí ń sanwó fún tààrà • Ṣíṣe ìṣòwò ìdáná tìrẹ ní ìgbà oru*

Ìwọ̀nyí ni orísun ***owó àpawọlé láti iṣẹ́-àdáni.*** Tí o bá dáhùn bẹ́ẹ̀ni sí èyíkéyìí nínú ìwọ̀nyí, tẹ "àdáni" wọlé nínú abala agbanisíṣẹ́ ti ìbéèrè náà kí o sì jábọ̀ àwọn iye owó àmúrelé.

**BÍ O TI LE ṢÍRÒ OWÓ ÀMÚRELÉ LÁTI IṢẸ́-ÀDÁNI**

1. Bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àpapọ̀ iye owó tó wá sínú òwò rẹ ní ọdún kan. (Lórí fọ́ọ̀mù owó orí 1099, èyí ní "àpapọ̀ ohun àgbàwọlé.")
2. Yọ àwọn ìnáwó ìṣòwò kúrò àti àwọn àyọkúrò.
3. Èyí ni ***owó àmúrelé láti iṣẹ́-àdánirẹ***.



**Kínní agbaṣẹ́ṣe aládàáni?**

***Agbaṣẹ́ṣe aládàáni*** jẹ́ ẹnìkan tí àwọn míràn ń yá láti ṣe àwọn iṣẹ́ kan nígbàtí wọ́n bá nílò wọn. Agbaṣẹ́ṣe àti ẹni tí ń yá wọn máa ń sábà ní àdéhùn tàbí ìléri kan.

**Àpẹrẹ: Nicole Kunlé-kunlé**

Nicole jẹ́ Kunlé-kunlé ó si ń ṣiṣẹ́ bíi ***agbaṣẹ́ṣe aládàáni***. Ó ní gbogbo irinṣẹ́ bíi búrẹ̀ṣì, àkàbà, àti ohun èlò míràn, àwọn ènìyàn sì ǹ pèé láti kun àwọn ilé wọn. Kí ó tó bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ìkunlé fún ẹnikẹ́ni, wọ́n ti ṣe àdéhùn lórí iye tí yóò gbà fún wákàtí kan wọ́n sì ti bu ọwọ́ lu ìwé. Nígbàtí Nicole bá parí kíkun ilé, yóò sọ fún ẹni náà iye wákàtí tó fi ṣiṣẹ́, ẹni náà yóò sì kọ ìwé sọ̀wédowó kan fún un tàbí fún un ní owó.

**RÁNTÍ**

Lórí ìbéèrè náà, owó àpawọlé láti iṣẹ́-àdáni gbọ́dọ̀ jẹ́ **<u>lẹ́yìn</u>** ìṣòwò àti tí a ti ṣàyọkúrò àwọn ìnáwó kan. Èyí ni a ń pè ní ***owó àmúrelé***.

## ṢÍṢÍRÒ OWÓ ÀPAWỌLÉ LÁÀRÍN ỌDÚN LÁTI IṢẸ́-ÀDÁNI

O le má pa iye owó kannáà láti iṣẹ́-àdáni ní gbogbo ọdún. Ìyẹn dára. Lo àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí láti ṣírò owó àpawọlé ọdọọdún rẹ láti iṣẹ́-àdáni.

1. Wàá nílò ọdún 3 tó kọjá nínú ìlà kan ti àwọn ìdápadà owó-orí fún irú iṣẹ́-àdáni yìí.
   - *Tí o kò bá ní àlàyé fún ọdún 3, lo ọdún 2 tó kọjá nínú ìlà kan.*
2. Wo iye owó èrè àmúrelé lórí àwọn ìdápadà owó-orí.
   - *Lórí ìdápadà owó-orí, wo ìlà 12, "Owó àpawọlé ìṣòwò (tàbí àdánù)."*
   - *Lórí Ètò fọ́ọ̀mù C, wo ìlà 31, "Èrè àmúrelé(tàbí àdánù)."*
3. Ǹjẹ́ o rò wípé wàá pa <u>bíi iye</u> owó kannáà ní ọdún yìí bí o ti ṣe ní ọdún to kọjá? Tó bá jẹ́ bẹ́ẹ̀ni, ṣírò ìlàjì kí o sì ṣàfikún iye náà lórí ìbéèrè náà. (Wo ìsàlẹ̀ fún bí o ti le ṣírò ìlàjì)
4. Ṣé o ń retí iye owó ọdún yìí láti <u>yàtọ̀</u> sí ọdún tó kọjá? Tó bá jẹ́ bẹ́ẹ̀ni, ṣàfikún iye owó tí o ń retí láti pa ní ọdún yìí.
5. Tí o bá pàdánù owó ní ọdún kan, lo $0.00 fún ọdún náà. Máṣe lo nọ́mbà òdì. Wo "Nípa Àwọn Ìlàjì" nísàlẹ̀ fún ọ̀pọ̀ àlàyé.
6. Ṣàrídájú pé o ní àwọn ìwé àkọsílẹ̀ láti ṣàfihàn iye owó tí o ti pa tẹ́lẹ̀ (bíi àwọn ìdápadà owó-orí) àti iye owó tí o rò wípé wàá pa ní ọdún yìí (bíi lẹ́tà láti ọ̀dọ̀ olùṣírò owó rẹ tàbí adarí ìṣòwò, àkọsílẹ̀ ètò ìṣúná-owó, ètò-owó, tàbí àlàyé míràn).

**Àpẹrẹ: Iṣẹ́ Ìdáná ti Dafidi**



Dafidi ń ṣiṣẹ́ fún ìjọba láàrín ọ̀sẹ̀, ṣùgbọ́n ní ọdún díẹ̀ sẹ́yìn ó tún bẹ̀rẹ̀ òwò oúnjẹ sísè ní òpin ọ̀sẹ̀ ìgbà oru láti pa àfikún owó. Òwò náà ń dàgbà.

Ní ọdọọdún òwò Dafidi ń pa owó tó pọ̀ jù ti ọdún tó kọjá lọ:

- ọdún 3 sẹ́yìn, òwò náà pa $5,000.00
- ọdún 2 sẹ́yìn, ó pa $7,000.
- Ọdún tó kọjá, ó pa $9,000.

Nítorí ìrírí ọdún 3 sẹ́yìn yìí, Dafidi ń retí láti pa $11,000 ní ọdún yìí láti iṣẹ́ iná dídá. Ó gbọ́dọ̀ fi $11,000 sórí ìwé ìbéèrè níbití ó ti tẹ owó àpawọlé iṣẹ́-àdáni rẹ̀. Eyí jẹ́ àfikún sí owó oṣù tí ń gbà lẹ́nu iṣẹ́ ìjọba rẹ̀.

## NÍPA ÀWỌN ÌLÀJÌ

Tí o bá rò wípé wàá pa iye kannáà ní ọdún yìí bíi tí ọdún 3 sẹ́yìn, ṣírò ìlàjì àwọn ọdún náà kí o sì tẹ̀ẹ́ wọlé sínú ìwé ìbéèrè rẹ.

Èyí ni bí o ti le ṣeé:

1. Wá iye owó èrè àmúrelé lórí àwọn ìdápadà owó-orí rẹ láti ọdún 2 tàbí 3 sẹ́yìn lórí ìlà kan.
2. Ṣàròpọ̀ gbogbo iye owó náà.
   - *Ǹjẹ́ èyíkéyìí iye náà jẹ́ òdì bí (Àpẹrẹ: $ - 924.00)? Tó bá jẹ́ bẹ́ẹ̀ni, lo $0.00 fún ọdún náà dípò.*
3. Pín nọ́mbà náà pẹ̀lú iye owó àpawọlé tí o fi bẹ̀rẹ̀.
   - *Tí o bá ní iye owó láti ọdún **<u>3</u>**, pín nọ́mbà náà pẹ̀lú 3 láti rí ìlàjì.*
   - *Ití o bá ní iye owó láti ọdún **<u>2</u>**, pín nọ́mbà náà pẹ̀lú 2 láti rí ìlàjì.*
4. Ṣàtẹ̀wọlé ìlàjì sínú abala "Owó àpawọlé láti Iṣẹ́-Àdáni" ti ìwé ìbéèrè rẹ.

# 3 Owó àpawọlé láti Àwọn Orísun Míràn



Ìwọ tàbí àwọn ènìyan tí wàá gbé pẹ̀lú wọn le ní owó àpawọ́lé tí kò wá láti iṣẹ́ kan tàbí iṣẹ́-àdáni. Tí o bá gba èyí ***owó àpawọlé láti àwọn orísun míràn*** ní ***ìgbàdégbà,*** o tún gbọ́dọ̀ ṣàfikún rẹ̀ lórí ìbéèrè rẹ.

**Ǹjẹ́ ìwọ, tàbí èyíkéyìí àwọn ènìyàn tí yóo gbé pẹ̀lú rẹ, ń gba owó àpawọlé ní ìgbàdégbà láti...?**

*Àkíyèsí: Ṣàfikún owó àpawọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn ọmọdé lábẹ́ ọdún 18.*

- ☐ Owó ìkọ̀sílẹ̀
- ☐ Ìsanwó Òpin Ọdún
- ☐ Àwọn Ìpamọ́ Iṣẹ́ Ológun
- ☐ Àtìlẹ́yìn Ọmọdé*
- ☐ Ìdójútòfò Abarapá
- ☐ Àwọn Ìpínkiri
- ☐ Owó àjẹmọ́nú
- ☐ ***Àwọn ẹ̀bùn***
  - ➤ *Àwọn àpẹẹrẹ ní ojú ìwé tókàn*
- ☐ ***Ẹ̀rè láti Ìṣòwò*** (bíi àwọn àkọ́ọ́lẹ̀ ilé-ìfowópamọ́ tàbí àwọn ìdókòwò míràn)
  - ➤ *Ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé síi ní ojú ìwé.10, "Àwọn ọ̀rọ̀ Ìrànlọ́wọ́"*
- ☐ Ìfẹ̀yìntì
- ☐ Ìrànlọ́wọ́ Ìjọba (PA)**
- ☐ Ohun ìní Tí A Yá Ni
  - ➤ *Lo owó àmúrelé láti ohun ìní tí a yá ni*
- ☐ Ààbò Ìgbàlódé tàbí SSI
  - ➤ *Lo ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ owó fún oṣù kọ̀ọ̀kan, sáájú àwọn àyọkúrò*
- ☐ Àwọn Ànfàní Àìníṣẹ́
- ☐ Ìsanwó Òṣìṣẹ́

Ìwọ̀nyí ni àwọn àpẹrẹ ***owó láti àwọn orísun míràn***. Tí o bá sọ "bẹ́ẹ̀ni" sí èyíkéyìí ìwọ̀nyí, ṣàfikún iye owó náà nínú abala "Owó àpawọlé láti Àwọn Orísun Míràn" ti ìbéèrè rẹ.

**RÁNTÍ**

- Ṣàfikún ***owó láti àwọn orísun míràn*** nìkan tí o bá gbàá láti ***igbà-dé-igbà*** (bíi ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀, ọ̀sẹ̀ méjì méjì, oṣooṣù, tàbí ọdọọdún). Máṣe ṣàfikún ***àwọn ìsanwó onígbà kan***.
- Lórí ìbéèrè náà, ṣàfikún iye owó tí wàá gbà ní ọdún kan gbáko láti orisun kọ̀ọ̀kan. Ṣe èyí kódà tí o kò bá gba owó náà fún ọdún kan gbáko.

  *Fún àpẹrẹ: YO ń gba ìsanwó àìníṣẹ́ ní gbogbo ọ̀sẹ̀, ṣùgbọ́n o mọ̀ pé ìsanwó náà yóò dópin ní oṣù díẹ̀. Ṣàfikún gbogbo iye owó tí wàá gbà ní ọdún kan tí ìsanwó náà kò bá ní dópin. Lọ sí ojú ìwé.4 láti kọ́ bí o ti le ṣírò owó àpawọlé ọdọdún láti ìsanwó ìgbàdégbà.*

** Ṣé o gba àṣẹ ilé-ẹjọ́ fún àtìlẹ́yìn ọmọ bí àti ìrànlọ́wọ́ ìjọ́ba (PA)? Ṣàrídájú pé o gba ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ iye owó náà ti àtìlẹ́yìn ọmọ tí a san. Fún àpẹrẹ, tí o bá gba ìsanwó "jẹ́ kí ń kọjá" kan, ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ owó ti àtìlẹ́yìn ọmọ tí a san le yàtọ̀ sí ohun tí o ń gbà ní oṣoṣù.*

*** Owó ìrànlọ́wọ́ ìjọba rẹ ni a ó ṣírò gẹ́gẹ́ bí òfin fún àwọn àdúgbò "bí a ti sanwó" náà. Tí o bá lọ sínáà **ìpàdé láti ṣàrídájú àmúyẹ rẹ**, aṣojú olùkọ́lé tàbí olùtajà yóò wo gbogbo ìwé àkọsílẹ̀ rẹ láti ṣe ìṣírò yìí.*

**Kínni owó àpawọlé ẹ̀bùn?**

Tí àwọn ènìyàn tí o kò bá gbé ilé bá fún ọ ní owó tàbí ṣèrànwọ́ láti san gb[[esè rẹ ní ***ìgbàdégbà***, èyí ni ***owó àpawọlé ẹ̀bùn.*** O gbọ́dọ̀ ṣàfikún rẹ̀ nínú ìṣirò owó àpawọlé.



**Àwọn àpẹrẹ:**

- Àwọn òbí rẹ ń sanwó iná rẹ ní oṣoṣù, ìlàjì rẹ̀ sì jẹ́ bíi $100 lóṣù. O gbọ́dọ̀ ṣàfikún $100 lóṣù nínú owó àpawọlé rẹ lórí ìwé ìbéèrè rẹ.
- Ọ̀rẹ́ kan tàbí mọ̀lẹ́bí fún ọ ní $20 ní ọ̀sọ̀sẹ̀ láti ṣèrànwọ́ pẹ̀lú àwọn ìnáwó rẹ. O gbọ́dọ̀ ṣàfikún $20 lọ́sẹ̀ nínú owó àpawọlé rẹ lórí ìwé ìbéèrè rẹ.

Tí a bá fìwépè ọ́ fún ***ìpàdé láti ṣàrídájú àmúyẹ rẹ***, wàá nílò àwọn ìwé àkọsílẹ̀ láti jẹ́rìísí pé o gba owó àpawọlé ẹ̀bùn yìí nígbàdégbà. Fún àpẹrẹ, ṣàrídájú pé o sanwó sínú àkọ́ọ́lẹ̀ ilé-ìfowópamọ́ rẹ kí àkọsílẹ̀ àkọ́ọ́lẹ̀ rẹ le ṣàfihàn pé a ń sanwó fún ọ nígbàdégbà. O le ṣàrídájú pé ẹlòmíràn san gbèsè fún ọ pẹ̀lú ẹ̀dà àwọn ìwé sọ̀wédowó wọn tí a fagilé.

*Àkíyèsí: Ìwọ̀nyí <u>kìíṣe</u> owó àpawọlé ẹ̀bùn a kò sì gbọ́dọ̀ ṣàfikún rẹ̀ nínú ìṣirò owó àpawọlé rẹ: Àwọn ẹ̀bùn (1) ti oúnjẹ fún àwọn ọmọdé nínú mọ̀lẹ́bí rẹ, (2) iye owó oúnjẹ ọ̀sán tí a dínkù tàbí tó jẹ́ ọ̀fẹ́, tàbí (3) iye owó oúnjẹ tí a ń pèsè fún àwọn arúgbó tàbí aláìní.*

---

# Owó Àpawọlé Tí A Kò Ṣàfikún



**Àwọn ìyọ̀nda kan wá sí ohun tí a ṣàfikún bíi owó àpawọlé:**

- Owó àpawọlé láti ẹnu iṣẹ́ fún àwọn ọmọdé tí kò tó ọdún 18
- Èyíkéyìí owó àpawọlé tó ju $480 lọ tí ẹnití a ń bọ́ kan ń gbà ***ọmọ ilé-ìwé*** tó ju ọdún 18 lọ
- Àwọn owó àsanpọ̀
  *Àwọn àpẹrẹ: Owó àsanjáde adójútòfò • Ogún jíjẹ́*
- Owó onígbà kan, tí kìíṣe àsantúnsa, tàbí owó púpọ̀ (pẹ̀lú ***àwọn ẹ̀bùn ọjọ́-kan***)
- Àwọn ìsanwó tàbí owó àsanpadà fún àwọn ìnáwó ìlera
- Àwọn ìsanwó fún títọ́jú àwọn ọmọ aláìlóbìí
- Ìrànlọ́wọ́ ọmọ ilé-ìwé tí a san fún ọmọ ilé-ìwé tàbí ilé-ẹ̀kọ gíga
- Iye owó dọ́là ti àwọn èdìdí oúnjẹ tàbí SNAP
- Àwọn ẹ̀bùn oúnjẹ fún àwọn ọmọdé nínú mọ̀lẹ́bí rẹ
- Iye owó oúnjẹ ọ̀sán ti ilé-ìwé èyítí a dínkù
- Iye owó oúnjẹ tí a pèsè fún àwọn arúgbó tàbí aláìní

**Máṣe ṣàfikún àwọn nkan wọ̀nyí nínú ìṣirò owó àpawọlé rẹ.**

---

# Àwọn Ìbéèrè Tí A Ń Bèrè Nígbà Gbogbo

## OWÓ ÀPAWỌLÉ LÁTI ẸNU IṢẸ́-ÒJÒJỌ́

**Kínní dé tí mo fi ní láti tọpinpin *owó àpawọ̀lé ọdọdún mi*? Ṣé ń kò le ṣàà fi owó tí mo pa ní ọdún tókọjá síi?**

Ìwọ àti àwọn ènìyàn tí ẹ dìjọ ń gbé papọ̀ yóò ***yẹ*** èyí dá lórí iye owó tí ẹ ó pa ní ọjọ́ iwájú. Ó jẹ́ ohun tó dára láti wo àwọn àkọsílẹ̀ owó-orí láti ọdún tó kọjá, ṣùgbọ́n èyí kò tó. Ọdún kọ̀ọ̀kan yàtọ̀. Ìdí ni èyí tí o fi gbọ́dọ̀ tẹ iye owó tí o ń gbà lọ́wọ́lọ́wọ́ wọlé, tí ìgbà tí o máa ń gba owó. Ó tún jẹ́ ìdí tí o fi gbọ́dọ̀ ṣàfikún owó àjẹmọ́nú tí o gbà tàbí tí o retí láti gbà ***nígbàdégbà,*** àti ***owó àpawọlé láti àwọn orísun míràn***.

**Ọmọbìnrin mi àgbà jẹ́ ọmọ ilé-ìwé ààrọ̀ tí ń ṣiṣẹ́ lẹ́yìn ilé-ìwé. Ṣé owó rẹ̀ pẹ̀lú bí?**
Tí ọmọ ilé-ìwé kan tó ju ọdún 18 lọ bá jẹ́ ọmọ tó sì gbẹ́kẹ̀lé òbí tàbí alágbàtọ́, owó $480 ti ***iowó àpawọlé láti ẹnu iṣẹ́-òòjọ́*** nìkan ni a ṣàfikún bíi owó àpawọlé.

**Mo ń fi ọwọ́ gba owó. Báwo ni mo ti le jẹ́rìísí pé èyí ni owó àpawọlé mi?**
Ó ṣe pàtàkì láti máa tọ́jú àkọsílẹ̀ owó àpawọlé tí o fi ọwọ́ gbà. Ìgbà gbogbo tí o bá fi ọwọ́ gba owó, kọ iye owó náà sílẹ̀, ọjọ́, àti ẹni tó san owó náà fún ọ. Tọ́jú àkọsílẹ̀ owó tí o fi ọwọ́ gbà yìí sí ibi tó wà lábẹ́ ààbò.

Tí o bá ní àkọ́ọ̀lẹ̀ ilé ìfowópamọ́, fi owó náà sí ilé ìfowópamọ́ lójú ẹsẹ̀. Èyí rí bẹ́ẹ̀ kí ilé ìfowópamọ́ le ní àkọsílẹ̀ wípé o ń gba owó nígbàdégbà. Ó dára tí o bá fẹ́ gba owó náà jáde kúrò nínú ilé ìfowópamọ́ rẹ lẹ́yìn náà. Ìwé àkọsílẹ̀ ilé ìfowópamọ́ rẹ yóò ṣàfihàn owó àsanwọlé náà.

<u>Rántí:</u> Tí o bá ń pa ju iye owó àpawọlé kan pàtó lọ, o tún gbọ́dọ̀ jábọ̀ rẹ̀ lórí ìdápadà owó-orí. Àwọn fọ́ọ̀mù owó-orí rẹ yóò sọ ohun tí owó náà wà fún.

**Mo ń gba owó *nígbà kọ̀ọ̀kan* ni. Báwo ni mo ti le ṣírò owó àpawọlé mi?**
Ó le nira láti ṣírò owó àpawọlé ọdọdún rẹ tí o kò bá gba owó ***nígbàdégbà***. Ìṣiṣẹ́ fún olùdáná ní àwọn òpin ọ̀sẹ̀ kọ̀ọ̀kan láti pa àfikún owó, ojojúmọ́ (lójúmọ́) àwọn iṣẹ́ ìlera, iṣẹ́ ìgbà díẹ̀, àti iṣẹ́ ọ̀ṣẹ́ré le jẹ́ àwọn àpẹẹrẹ iṣẹ́ ìgbà kọ̀ọ̀kan tàbí àìṣedéédé tí o ṣe fún agbanisíṣẹ́ kan.

Ṣé o ti gba owó lórí iṣẹ́ àìṣedéédé tàbí ìgbà kọ̀ọ̀kan rí bí ọdún 3 sẹ́yìn? Tó bá rí bẹ́ẹ̀, ṣàfikún iye náà tí o pa fún gbogbo ọdún mẹ́ta náà papọ̀ kí o sì pín in nípasẹ̀ 3. Nọ́mbà yìí jẹ́ ìlàjì owó àpawọlé rẹ láàrín ọdún láti ibi iṣẹ́ náà. Lẹ́yìn náà ṣírò iye tí wàá pa ní ọdún yìí láti irú iṣẹ́ kannáà. Ṣàfiwé nọ́mbà náà sí ìlàjì ọdọdún rẹ. Èwo ni ó pọ̀ jù? Lo nọ́mbà tó pọ̀ jù nínú abala “Owó Àpawọlé láti Iṣẹ́ Òòjọ́” ti ìbéèrè rẹ.

**Wkínni yóò ṣẹlẹ̀ tí owó àpawọlé mi bá yípadà lẹ́yìn tí mo bèrè, tí wọ́n sì pé mi sí*ìpàdé láti jẹ́rìísí àmúyẹ mọ̀lẹ́bí mi*?**
Tọ́jú gbogbo àwọn ìwé náà àti àwọn àkọsílẹ̀ tó jẹ́rìísí owó tí o ń gbà báyìí. Tí owó àpawọlé rẹ bá yípadà (fún àpẹẹrẹ, iṣẹ́ titun tàbí àfikún owó), tún mú àwọn àkọsílẹ̀ wá tí ń ṣàfihàn iye owó tí wàá máa gbà ní ọjọ́ iwájú. Aṣojú olùkọ́lé tàbí olùtajà yóò tún ṣírò owó àpawọlé rẹ.

## OWÓ ÀPAWỌLÉ LÁTI IṢẸ́-ÀDÁNI

**A ti fi ìwé pè mí sí *ìpàdé kan láti ṣàrídájú àmúyẹ mọ̀lẹ́bí mi* fún ilé àìwọ́n. Irú àwọn ìwé àkọsílẹ̀ wo ni mo nílò láti ṣàrídájú owó àpawọlé iṣẹ́-àdáni mi?**
Wàá ní láti ṣàrídájú iye owó tí o ti pa sẹ́yìn láti irú iṣẹ́ yìí, àti iye owó tí o ń retí láti pa ní ọdún yìí.

Láti ṣàrídájú iye owó tó kọjá, mú ọdún 3 rẹ tó kọjá wá lórí ìlà kan ti àwọn ìdápadà owó-orí fún iṣẹ́-àdáni nínú irú iṣẹ́ yìí. O le mú àlàyé wá láti ọdún 2 sẹ́yìn lórí ìlà kan tí o kò bá ní 3.

Láti ṣàrídájú iye owó tí o ń retí láti pa ní ọdún yìí, mú lẹ́tà kan wá láti ọ̀dọ̀ olùṣírò owó rẹ tàbí adarí ìṣòwò rẹ, àwọn àkọsílẹ̀ ètò-ìṣúná, ètò-owó, ìwé-ẹ̀rí ọjà, tàbí àlàyé míràn tí ń ṣàtìlẹ́yìn fún owó tí o retí láti pa.

**Tí mo bá ti ní iṣẹ́-àdáni mi ní irú iṣẹ́ kan pàtó tẹ́lẹ̀ tó kéré ju ọdún 2 lọ?**
Wàá nílò àwọn àkọsílẹ̀ tí ń ṣàfihàn ìyẹn, ní ọjọ́ ìpàdé rẹ, o ti ní iṣẹ́-àdáni tìrẹ fún irú iṣẹ́ yìí fún ọdún 2 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Tí o kò bá le pèsè àlàyé yìí láti ọdún 2 tó kọjá lórí ìlà kan, ó ṣeéṣe kí o má yẹ.

Kódà tí o bá rò pé èyí le jẹ́ bẹ̀, o sì gbọ́dọ̀ ṣàfikún ***owó àmúrelé láti iṣẹ́-àdáni*** lórí ìwé ìbéèrè náà. Máṣe fi èyíkéyìí owó àpawọlé kankan sílẹ̀. Ó le gbà tó ọ̀pọ̀ oṣù kí o tó gbọ́ láti ọ̀dọ̀ wa tí nọ́mbà rẹ bá jẹyọ nínú tẹ́tẹ́ oríire náà, fún ìdí èyí ó le ṣeéṣe pé wàá ní ọdún 2 ti owó àpawọlé iṣẹ́-àdáni ní àkókò náà. Ṣàrídájú láti mú àwọn ìwé àkọsílẹ̀ wá sí ibi ìpàdé náà tí ń ṣàfihàn iye tí o ti pa tẹ́lẹ̀ láti irú iṣẹ́ yìí ti iṣẹ́-àdáni, àti iye owó tí wàá pa ní ọdún yìí.

ÀWỌN GBÓLÓHÙN ÌRÀNWỌ́

# Àwọn gbólóhùn ìrànwọ́

**Agbaṣẹ́ṣe Aládàáni** Ẹnìkan tàbí ìṣòwò tí àwọn míràn ń yá láti ṣe irú ìṣẹ́ kan nígbàtí wọ́n bá nílò wọn. Nítòótọ́ agbaṣẹ́ṣe náà àti ẹni tí ń yá wọn máa ń ní àdéhùn tàbí ọ̀rọ̀ àjọṣọ kan.

**Àwọn ohun ìní:** Àwọn ohun ìní jẹ́ àwọn nkan pàtàkì tí o ní èyítí a le yípadà sí owó. Àkọ́ọ́lẹ̀ ìpamọ́ owó jẹ́ ohun ìní Ilé ìfowópamọ́ máa ń san èrè lórí ohun ìní. Èrè náà jẹ́ owó àpawọlé láti orí ohun ìní náà. Àwọn àpẹẹrẹ míràn: ìpín òwò, ìdókówò, owó àjọdá, àwọn àkọ́ọ́lẹ̀ ọjà owó. Wo ***Èrè láti Orí Àwọn Ohun Ìní***, nísàlẹ̀, fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé.

**Èrè láti Àwọn Ohun Ìní:** Tí o bá lọ fún ìpàdé kan láti ṣàrídájú àmúyẹ, olùkọ́lé tàbí aṣojú olùtajà yóò ṣírò èrè owó àpawọlé rẹ láti inú àwọn ohun ìní bíi àwọn àkọ́ọ́lẹ̀ ilé ìfowópamọ́ àti àwọn òwò míràn. Tí gbogbo àwọn ohun ìní rẹ bá kéré sí $5,000, èrè tí wọ́n gbà ni a fikún owó àpawọlé rẹ. Tí gbogbo àwọn ohun ìní rẹ bá ju $5,000 lọ, yálà ko jẹ́ wípé èrè tí wọ́n gbà tàbí 0.06% ti iye tó jẹ́ ni a ń fikún owó àpawọlé rẹ, èyíkéyìí owó tó bá pọ̀ jù.

**Ilé Àìwọ́n:** Ilé ní New York City fún àwọn eniyàn tí owó àpawọlé wọn wá lábẹ́ iye kan pàtó. Nítòótọ́, ilé ni a ń pè ní "àìwọ́n" tí ènìyàn kan bá san bíi ìdáméta owó àpawọlé rẹ̀ fún owó ilé tàbí iye tí ilé náà jẹ́.

**Ìpàdé láti Ṣàrídájú Àmúyẹ:** Léyìn tí ìbéèrè náà ti dópin, gbogbo àwọn ìwé ìbéèrè ni a dá papọ̀. Bíbẹ̀rẹ̀ láti òkè àkójọ náà, àwọn ìwé ìbéèrè ni a ń ṣàyẹ̀wò àti bóyá wọ́n ṣeé kà, àwọn olùbèrè ni a ó pè fún ìpàdé láti tẹ̀síwájú ìlànà yíyẹ̀wò. Tí a bá pè ọ́ fún ìpàdé kan, wàá ní láti mú ìwé àkọsílẹ̀ tí ń ṣàrídájú owó àpawọlé rẹ.

**Ìsanwó Onígbà Kan:** Owó àpawọlé tí a kò gbà nígbà gbogbo láti ẹ̀yìn wá àti pé o kò rò láti tún gbàá ní ọjọ́ iwájú. Owó yìí ni a kò ṣàfikún sínú ìṣirò owó àpawọlé.

**Múyẹ/Mímúyẹ:** Owó rẹ gbọ́dọ̀ wà láàrín òdíwọ̀n pàtó kan kí ó sì bá àwọn àmúyẹ ìbéèrè míràn mu láti yẹ fún ilé àìwọ́n. Àwọn àmúyẹ míràn pẹ̀lú pípèsè àwọn ìwé àkọsílẹ̀ láti jẹ́rìísí owó àpawọlé rẹ àti láti yege àyẹ̀wò gbèsè àti àwọn ohun àtẹ̀yìnwá.. Tí ìwọ àti àwọn ènìyàn tí ń gbé pẹ̀lú rẹ bá kójú òṣùwọ̀n gbogbo àwọn ohun àmúyẹ, o ti yẹ.

**Ọmọ ilé-ìwé:** Ẹnìkan pẹ̀lú ipò ọmọ ilé-ìwé ní àárọ̀ (gẹ́gẹ́ bíi ilé-ìwé ọmọ náà) fún oṣù 5 ti kàlẹ́ndà ọdún náà. Oṣù 5 náà kò ní láti jẹ́ léraléra. $480 nìkan ti owó àpawọlé ọmọ ilé-ìwé tó dá wà láti ẹnu iṣẹ́ ni a fikún ìṣírò owó àpawọlé náà.

**Onígbàdégbà/Ìgbà Gbogbo:** Tí o bá gba owó àpawọlé láti èyíkéyìí orísun nígbàdégbà, tàbí "ìgbà gbogbo," èyí túmọ̀ sí a ń sanwó fún ọ ní àkókò tàbí ìgbà tó ṣe déédé. Owó àpawọlé tí a ń san ní ojojúmọ́, ọ̀sọ̀sẹ̀, ọ̀sẹ̀ 2, ẹ̀mejì ní oṣù, ẹ̀kan ní oṣù, oṣù mẹ́ta mẹ́ta, tàbí ní ọdọdún jẹ́ àwọn àpẹẹrẹ owó tí a ń san nígbàdégbà.

**Owó Àmúrelé:** Iye owó àpawọlé tí o gbà léyìn tí o ti yọ owó-orí kúrò, àwọn ìnáwó, àti àwọn àyọkúrò míràn. Owó àmúrelé ni a ń lò láti ṣírò owó àpawọlé láti iṣẹ́-àdáni.

**Owó Àpapọ̀** Àwọn àpapọ̀ (ọdọdún) ohun tí o ń gbà ní ọdún, owó ọ̀sẹ̀, ìsanwó, tàbí owó míràn tí o gbà láti ibi iṣẹ́ àti àwọn orísun míràn, kí a tó yọ èyíkéyìí owó-orí kúrò. Èyí máa ń ṣábà ju owó àmúrelé rẹ lọ. Ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn máa ń jábọ̀ owó àpapọ̀ lórí àwọn ìwé ìbéèrè wọn. Àwọn ènìyàn tí wọ́n ní iṣẹ́-àdáni máa ń jábọ̀ owó àmúrelé láti iṣẹ́-àdáni dípò.

**Owó Àpawọlé Ẹ̀bùn** Owó àpawọlé tí o gbà nígbà dégbà láti ọ̀dọ̀ ẹnìkan tí kò gbé pẹ̀lú rẹ. Fún àpẹẹrẹ: Àwọn òbí rẹ ń sanwó ohun èlò rẹ ní oṣoṣù, tabí ọ̀rẹ́ tàbí mọ̀lẹ́bí kan ń fi ìwé sọ̀wédowó kan ránṣẹ́ sí ọ láti ràn ọ́ lọ́wọ́ pẹ̀lú àwọn oúnjẹ àti àwọn ìnáwó míràn nígbàdégbà. Owó àpawọlé ẹ̀bùn le jẹ́ owó ní ọwọ́, ṣùgbọ́n kò ní ṣe kó jẹ́ bẹ̀.

**Owó àpawọlé Ìgbà Kọ̀ọ̀kan:** Owó àpawọlé tí a kò san ní ìgbà kan pàtó tàbí ìgbà tí a ń retí. Àwọn iṣẹ́ onígbà díẹ̀, iṣẹ́ ìgbà òjò tàbí ẹ̀rùn, tàbí àwọn iṣẹ́ ìṣeré le jẹ́ àwọn àpẹẹrẹ iṣẹ́ tí ń yọ léraléra ṣùgbọ́n tí a ń sanwó rẹ̀ nígbà kọ̀ọ̀kan.

**Owó àpawọlé láti Àwọn Orísun Míràn:** Owó àpawọlé tí o gbà nígbàdégbà tí kò wá láti orí iṣẹ́ kan. Fún àpẹẹrẹ, Àwọn ànfàní arúgbó tàbí Ààbo Ìgbàlódé, ìrànlọ́wọ́ ìjọba, tàbí àtìléyìn ọmọdé.

**Owó àpawọlé láti Iṣẹ́-Àdáni** Owó àpawọlé tí o pa láti ṣiṣẹ́ fún ara rẹ, láti ní òwò ti ara rẹ, tàbí láti pèsè iṣẹ́. Èyí pẹ̀lú ṣíṣe iṣẹ́ fún oríṣiríṣi agbanisíṣẹ́ láti ìgbà-dé-ìgbà, iṣẹ́ àkànṣe aládàáni, àti iṣẹ́ fún yíyá míràn. Owó àmúrelé ni a ń lò fún owó àpawọlé láti iṣẹ́-àdáni lórí ìwé ìbéèrè rẹ. Tí owó àmúrelé rẹ bá jẹ́ $400 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ ní ọdún kan, o gbọ́dọ̀ jábọ̀ owó àpawọlé náàlórí ìwé ìbéèrè rẹ. *Àkíyèsí: ití ìṣòwò rẹ bá jẹ́ S-corporation, owó àpapọ̀ ìṣòwò tí a jábọ̀ lórí Schedule K-1 ni a lò láfikún sí àpapọ̀ W-2 owó tí o gbà.*

**Owó àpawọlé láti Iṣẹ́-òòjọ́:** Owó àpawọlé fún iṣẹ́ tí o ṣe fún agbanisíṣẹ́ kan (kìíṣe fún ara rẹ). Owó àpapọ̀ ni a ń lò láti jábọ̀ owó àpawọlé láti iṣẹ́-òòjọ́.

**Owó àpawọlé:** Ohun tí o pa, owó ọ̀sẹ̀, ìsanwó, tàbí owó míràn tí o gbà.

**Owó Ọdọdún:** Iye owó tí a san fún ọ ní ọdún kan, tí a ṣírò láti owó àpapọ̀ láti iṣẹ́-òòjọ́, owó àmúrelé láti iṣẹ́-àdáni, àti owó àpawọlé láti àwọn orísun míràn.

NYC Housing Connect

www.nyc.gov/housingconnect

Wá kí o sì Bèrè fún Ilé Àìwọ́n

Department of Housing Preservation & Development

NYC HDC NEW YORK CITY HOUSING DEVELOPMENT CORPORATION

facebook.com/NYCHPD

@nychousing

www.nyc.gov/housingconnect
www.nyc.gov/hpd

Ṣàbẹ̀wò sí www.nyc.gov/housingconnect láti rí ọpọ àlàyé tàbí bèrè lórí ayélujára.

Àkọsílẹ̀ yìí wà fún èrèdí àlàyé nìkan. Èyí kìíṣe ìbéèrè fún ilé àìwọn. Kíkọ àwọn ohun tí a bèrè fún sínú ìwé yìí kìí ṣe ìdánilójú pé wàá gba ibùgbé àìwọn kankan.